Bibeli fun awon omode

# Nigbati Olorun da ohun gbogbo



Ikosile gba owo: Edward Hughes
Ayaworan: Byron Unger; Lazarus
Olu'lo: Bob Davies; Tammy S.
Atunmo ede: Oluwashina Oluwadimu
Alakoso: Bible for Children
www.M1914.org

BFC
PO Box 3
Winnipeg, MB R3C 2G1
Canada

©2013 Bible for Children, Inc.
Iwe ase: Oni ase lati se atunko tabi attune itan yi,
niwon igba ti o ko so di owo.

Tani oseda wa? Bibeli, oro Olorun, so bi iran eniyan se bere. Latetekose, Olorun da okunrin akoko osi pe oruko re ni Adamu. Olorun da Adamu lati inu erupe ile. Nigbati Olorun mi emi iye sinu Adamu, odi alaye okan. Ori ara re ninu ogba didara kan ti ape ni Edeni.



Ki Olorun t'oda Adamu, oda Ile aiye tokun fun ohun meremere.  Leselese Olorun da awon oke ati awon ile tokun fun ewe, fulawa oloorun didun ati awon igi nla, awon eiye alawo didara ati awon kokoro oyin, eja nla inu okun ati awon igbin.



Li ibere
ohungbogbo,
ki Olorun toda
ohunkohun, kosi
ohun kan afi Olorun.
Kosi Imole tabi
okunkun.  Kosi oke
kosi ile.  Kosi ana
kosi ola.  Olorun
tiko li ibere nikan
lowa.  Olorun sib
ere ise.



Latetekose,
Olorun da awon
orun ati aiye.

Aiye siwa ni juujuu osi sofo. Okunkun siwa loju ibu. Olorun si wipe "Jeki imole wa".



Imole siwa. Olorun pe imole li ojo ati okunkun li oru. Ati Asale ati owuro ojo akoko.



Li ojo keji, Olorun mu awon omi osa, okun and od bo si ipo won labe orun.  Li ojo keta, Olorun wipe, “Jeki Ile kofi ara han”.  Osi ri be.



Olorun p'ase wipe ki koriko ati ewebe ati igi ati igi eleso farahan. Won si farahan. Ati asale ati owuro ojo keta.



Olorun da oorun, ati osupa, ati awon irawo oju orun ti enikan kolee ka.  Ati asale ati owuro, ojo kerin.





Awon eda inu omi ati eja ati eiye li Olorun da.  Li ojo karun Olorun da eja nla ati kekere, eiye olorungigun and eiye kekeke.  Olorun da oniruru eja lati kun inu omi ati oniruru eiye lati gbadun ile, ati okun ati ofurufu.  Ati asale ati owuro odi ojo Karun.



Lehin eyi, Olorun tun wipe “Jeki ile mu oniruru eda alaye jade …” Oniruru eranko ati kokoro, ati eranko ti nrako si jade wa. Awon erin nlanla ati eran igbe. Awon obo ati oni ti nrako. Awon aran ati eran igbe. Awon Ologbo ati oniruru eranko igbe li Olorun da l’ojo na. Ati asale ati owuro li ojo kefa.



Olorun se ohun miran li ojo kefa – Ohun to yato. Ohun gbogbo lati pese fun eniyan. Ounje wa ni oko ati awon eranko ti yio sin. Olorun si so wipe, “Jeki ada eniyan li aworan ara wa. Jeki oje oluwa lori gbogbo ekun aiye.”

OLORUN DA ENIYAN LI AWORAN RE; LI AWORAN RE L’ODA ENIYAN …



Olorun wifun
Adamu pe.  "Je
ohungbogbo ninu
ogba.  Sugbon
mase je eso imo
rere ati ibi.  Bi o
ba je ninu re iwo
yio ku."



OLUWA Olorun si wipe, “Ko dara ki okunrin ki owa nikan. Emi yio se oluranlowo fun.” Olorun mu eiye ati eranko wa si odo Adamu. Adamu fi oruko fun gbogbo won. O gbodo ni laakaye lati se eyi. Sugbon laarin awon eiye ati eranko kosi eniti odabi Adamu.





Olorun fi orun ijika kun Adamu. Omu okan ninu iha re, Olorun da Obirin lati inu iha Adamu. Obirin ti Olorun da li oluranlowo fun Adamu.

Olorun da ohun gbogbo li ojo mefa. Olorun si bukun ojo keje osi pe ni ojo isimi. Ninu ogba edeni, Adamu ati Efa aya re ngbe ninu ayo nla, won ngboran si Olorun. Olorun je OLUWA won, olupese fun won ati ore won.



Nigbati Olorun da ohun gbogbo

Itan lati inu oro Olorun, Bibeli

lari ka ninu

Genesisi ori kini si ekeji (1-2)

“Iwole oro re funwa ni imole.”
Orin Dafidi 119:130

# Opin

Itan Bibeli yii so fun wa nipa Olorun
iyanu wa t'oda wa ti osi fe ki amo ohun.

Olorun mo wipe ati se ohun ibi, ti ope ni ese. Iku ni ere ese, sugbon Olorun feran re tobe ge tofi omo re kan soso, Jesu, ranse lati ku lori igi agbelebu ki osi jiya fun ese re. Jesu si pada wa si aaye osi losi ile l'orun! Bi o ba gbagbo ninu Jesu ti osi toro idariji ese re, Yi o se eyi! Yi o si wa gbe ninu re nisisiyi, iwo yio si gbe pelu re lailai.

Bi o ba gbagbo wipe otito ni eyi, so fun Olorun wipe:
Jesu mi owon, Mo gbagbo wipe ire ni Olorun, o di eniyan lati ku fun ese mi, osi wa laaye sibe. Jowo wa sinu aye mi ki osi dari ese mi jimi, ki emi ki oni aye otun nisisiyi, ati ni ojo kan ki emi kole wa pelu re titi lai. Ranmilowo lati gbo tire ati lati je omo o re. Amin.

Ka Bibeli re ki osi ba Olorun soro lojumo!
Johannu ori keta ese kerindinlogun.